# ELETI ỌFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 845 LAGOS SATURDAY NOVEMBER 10—NOVEMBER 16 1962 KỌBỌ MEJI (2d)


## Kere O ! Gbangba Dekun :

# Ijoba Apapose Tun Fe Gba Awon Ile Ati Ile Kakiri L'Eko

EKO— Gbangba d'ẹkun kedere fẹ bẹ ewo ; Ijọba Apapọse ti fi iwe ikede ṣita ni ijẹta wipe awon tun fẹ wo ile nitoripe awọn fẹ lo ilẹ ni igboro Eko fun ilọsiwaju ilu na.

Awọn adugbo ti nwọn fẹ lo na pọ 'diẹ lọtẹ yi ; o bẹrẹrẹ lati Olowogbowo, Ebute-Ero, Isalẹga ngan titi ti o fi de Ẹpẹtẹdo nibi ti awọn Minisifa gbe nsunle ni Dumaresque pẹlu Tapa Street, Freeman Street ati Igunnu Street.

Ti awọn ara Olowogbowo bẹrẹ lati ebute Ẹlẹgbata mọ Apọngbọn dapọ mọ adugbo kan ti nwọn pe ni Griffin Lane.

Ni Isalẹgangan, awọn Ijọba ni awọn fẹ lo ilẹ ni adugbo Okepopo, Ọdunfa, Ajanaku ati Oluṣi.

Ilẹ ti nwọn fẹ lo ni Ebute-Ero bẹrẹ ni ibi Kereni atijọ, Great Bridge, leti Ṣọṣi Ebute-Ero mọ Ashọgbọn Street loju Ọlọbun.

Nkan ti awọn Ijọba na fẹ lo awọn ilẹ yi fun ko ye wa rara, ṣugbọn awọn enia kan ni boya nwọn fẹ lo diẹ fun Kereni tuntun ti nwọn fẹ kọ ni. Ju gbogbo rẹ lọ, bi o ba ti ri a o ma sọ fun yin.


## LAGOS RACE CLUB

First Day

NIGERIAN TRADE FAIR RACE MEETING.

TODAY

First Race at 3 p. m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st will be paid £2. 10. 0d; 2nd £1. 10/- and 3rd 10/-.

**Come One Come All**

Hon. Secretary
Lagos Race Club.


## Awon Onifayawo Ti O Pa Olopa Gba Idajo Iku

ONITSHA— Ninu ọsẹ yi ni adajọ Kotu nla Ogbẹni H.U. Kaine ṣe idajọ wipe ki nwọn lọ yẹgi mọ awọn onifayawọ marun kan ti nwọn pa Ọlọpa ti o fẹ mu wọn lọjọ kan. Orukọ awọn onifayawọ na ni Patrick Nwafor Nwonwen, John Onuora Martin Ugwu ati Peter Ndubusi.

Irohin ti onirohin Eleti-Ofẹ fi ranṣẹ si wa nipa ẹjọ ti awọn Ọlọpa ba awọn Onifayawọ na ro ni pe lọjọ ti nkan yi ṣelẹ, awọn ran Bamford Amazama, Ọlọpa ti nwọn pa, lọ si agọ kan ti nwọn npe ni Ofe-Ukwu-akpu, agọ awọn baba Oni-fayawọ.

Nigbati ọlọpa yi de ibẹ, o fi ara ṣ'oko sinu igbo nibi kan ; ko pẹ lẹhin na o ri awọn arufin yi ti nwọn nko agba epo ti nwọn ji jade ninu ọkọ, o wa sun mọ wọn lati bere ibi ti nwọn ti nko awọn agba epo na bọ ati pe nibo ni nwọn nko lọ. Nigbati Ọlọpa yi ri wipe alaye wọn na di koko, o ni ki nwọn tele on kalọ si teṣan ọlọpa.

Awọn arufin na ni ki o pa awọn sile, ki o ma pa awọn sita, nwọn gbe owo ti o jọju fun un, ṣugbọn ọlọpa na kọ ọ, eyi ni o wa jẹ ki nwọn pa a, nwọn si ju oku rẹ sinu odo Ọya (Niger) ṣugbọn nwọn ko mọ wipe ẹnikan ri gbogbo nkan ti nwọn ṣe na. Ẹlẹri yi ni o ro gbogbo rẹ fun awọn Ọlọpa ki nwọn to ri awọn arufin yi ko.


RECORDS OF THE WEEK

78 R.P.M. at 7/- each

P 82462 H
Me Ungyaa / Otan Bebzebe Yi

P 82461 H
Oba Dziscefo / Odoyewu Bra
E.K.'S Band

P 82482 H
Nia Fufuo / M'ahoma Te
Casino Dance Band

45 R.P.M. at 6/9d each

P 382370 F
Kelewele / Anyi Di
Eddy Okonta and his Jofabro Star Aces.

P 382 305 F
Erora / Alamise
Adeolu and his Rio Lindo Orchestra.

PHILIPS
of course...
— the records of the century —
Philips Nigerial Ltd.
Head Office: PMB 1138
Apapa
Branch Office: P.O. Box 427
Enugu

# ELETI—OFE

ANJUWON KO ŞE WI LEJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABELS & TELOERAM
28 Kosoko Street, Lagos, "ELETI—QFE" LAGOS
P. O. Box 468 Phone 23370
VOL XIV. No 845, SATURDAY. NOV. 10, — NOV 16, 1962

## Baba Onijibiti Eso Dowo Nyin

Otitọ ọrọ bi isọkusọ ni o ma nri: lati bi ọsẹ meji ti awọn Alakoso Ijọba Apapọṣe ti şi ibi ifọja han ni Okun l'Eko fun gbogbo awọn onişowo agbaiye ni awa oniwe irohin "Eleti-Ọfẹ" tişe afiyesi ọpọlọpọ awọn enia wa ti o nlọ wo awọn orişirişi ọja ti nwọn patẹ sibẹ. Eyi si dun mọ wa pupọ nitoripe a ri wipe nipa lilọ sibẹ yio ma ki oju wa ki o la siwaju si, awa na yio mọ wipe işẹ ni ogun ti a şe fun işẹ, ao si le mura giri, ao tẹşẹ bọ şokoto lati şişẹ gẹgẹbi orilẹ-ede.

A ro wipe gbogbo ẹnyin ọkawe wa lọkunrin ati lobinrin ti ẹ lọ sibi ipatẹ-ọja awọn Oyinbo Ijọba agbaiye yi ti ri ọgbọn ko wipe ilu ti o ba jẹ wipe işẹ awọn awọn akọwe onikola (collar) ni o pọ, ebi ni pa nwọn nibẹ. Gbogbo ẹrọ işẹ iroko ti awọn Oyinbo yi ko wa ko nşe fun ere şişe rara, awọn alara papa nlo wọn lati fi reko fun nkan ọgbin lati ri onjẹ bọ awọn ara ilu wọn ni awọn şe wọn fun.

### Eso Re

Gbogbo iregbe ti a ti nwi yi dun, o wa ku ikilọ pataki kan ti a fẹ şe fun awọn enia wa-awọn BABA ONIJIBITI ti nwọn nru apo wayo kiri ati awọn ejẹnu dudu ti nwọn ko gbe apo lọwọ ti a nwọn npara ibi ipatẹ ọja yi lati da "ẸBIRIKI" lu awọn Oyinbo ajoji ti nwọn mu ọja orişirişi wa sile yi lati gba lọwọ wọn.

Ọpọlọpọ ọrọ abuku nipa awọn ti o nhu iru iwa bayi lati ba wa jẹ lọdọ awọn alejo wa yi ni a ti ngbọ kakiri. Iru iwa bayi ko si dara rara, abuku ni o nko bani gẹgẹbi orilẹ ede.

Lẹkansi, a şe ikilọ fun awọn enia wa ti o nkọwe owo-şişe si ilu okere ki nwọn şọra, ti nwọn ko ba ni nkan ra ki nwọn ye kọwe gba ẹru lọfẹ. Abuku lo nko bani.

## Aseju Baba Asete

Awọn agbalagba ni lati kekere ni a ti npa ekan Iroko nitoripe ti o ba d'agba tan kise pa. Owe yi ni o yẹ ki a pa fun ọrọ awọn ọmọ ile iwe-nla ti nwọn npe ni University of Nigeria ni Nsukka leti Enugu ti awọn alamojuto ile ẹkọ na ni ki olukuluku wọn ma lọ si ile wọn lẹhinti nwọn ti binu lu awọn olukọ wọn ti nwọn si fa wọn ni aşọ ya pẹrẹ pẹrẹ.

Ni oju wa, a ri wipe awọn ọmọde ti ode oni ko tilẹ gba ijanu mọ. Nwọn ko gbọ ẹkọ ti baba ati iya wọn. Orikikun ni o mba wọn dagba ti o si nsun ọpọlọpọ lọ si ọgba ẹwọn nitoripe nwọ ko mọ agba ni agba.

## Ko Ye Awa Na

Mo fara mọ ọrọ Ọgbẹni O. Ọladimeji ti o kan saara si nyin fun ọrọ enia kika (Census) ti ẹ şe alaye fun wa wipe ọrọ kan wa nidi kika ti nwọn ka enia na ti nwọn ko si gbe iyọri enia kika na jade.

Iso inu ẹku ni ọrọ na ko şe wi sita. Gbogbo awọn enia jake jado ilẹ Nigeria ni nwọn mọ wipe nkan mbẹ nidi ọrọ na şugbọn nkan ti o mbẹ nibẹ ni ko ye awa ọgbẹri rara.

A tun ngbọ kakiri wipe awọn enia kan ti sọ panpa lati sọ wipe awọn enia ipinlẹ ti awọn ni o pọ pupọju.

Ẹ jowọ a fẹ mọ iye awa enia ti o wa nilu Nigeria.

Emi ni,
R. Adejumọ.

Oko-Baba,
Ebute-Mẹtta

## Oro Ilorin Pelu Igbomina

Ẹ ba wa dupẹ lọwọ Olofintoto Eleti - Ọfẹ ti o jẹ ki a mọ bi ọrọ awa ọmọ Igbomina pẹlu ara Ilọrin ti nlọ si lori Ijọba Ibilẹ ti a ni ki nwọn pin fun wa.

Nitotọ ko si olowo ẹru kan ti yio fẹ ki ẹru ti on nmu sin kuro lọwọ on. Şugbọn ilọsiwaju ni awa nfẹ fun ilu wa pẹlu idagba soke kişe ọrọ ija.

Yio dun mọ wa bi awọn ara Ilọrin na ba le yan Ijọba Ibile fun wa ki a mọ ibiti a gbe nlọ.

Mo dupẹ lọwọ nyin fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
M. Defidi

Ebute-Metta

## Nwon Le Awon Akeko Ti Nwon Na Tisa

### Kuro Nile Iwe

NSUKKA —Gbogbo awọn ọmọ akẹkọ ile iwe-giga ti nwọn wa ni Nsukka leti Enugu (University of Nigeria) ni awọn Alamojuto ile-iwe na le kuro ni ile ẹkọ nitori orikunkun ati alaigbọran ti nwọn şe si awọn olukọ wọn.

Ọrọ ti a gbọ nipa rogbodiyan ti awọn ọmọ ile iwe na ni pe ni ọsẹ ti o kọja yi ni nwọn fi aake kọri wipe awọn ko lọ si ibiti nwọn gbe ti npejọ fun ẹkọ wọn nitori ofin ti awọn awọn alamojuto ilewe na fun awọn wipe awọn ko gbọdọ gba obinrin ni alejo ninu iyara ti awọn ngbe, a fi ninu gbọgan ile-ẹkọ.

Nwọn kọ onjẹ wọn silẹ, nwọn si lu awọn tişa ti o da si ọrọ na nwọn si fa wọn ni aşọ ya pẹrẹ pẹrẹ.

Irinwo awọn ọlọpa idagiri ni awọn Ijọba ko lọ si ilewe na lọjọ ti nwọn le awọn ọmọ ile ẹkọ na jade. Nwọn ni ẹnikẹni ninu wọn ti o ba fẹ tun pade si ile iwe na ki o kọwe wa.

## Oro Olotu :

Awa oniwe irohin yi faramọ iya lile jade ti nwọn le wọn jade nile ẹkọ-giga na, boya eyi le jẹ ẹkọ fun awọn ti o mbọ lẹhin. Nwọn ni ki nwọn lọ kọ bi a ti nşe nhuwa ti aiye le fi rọrun ni, nwọn ko ni ki nwọn lọ kọ iwa ipata.

Nitotọ gbogbo wa ni a mọ wipe AŞEJU ni BABA AŞETẸ

# Kabiyesi Oba Alake Ademola Keji (9)

## (Lati Owo Omo Abati)

### Ademola J'oba

Gẹgẹbi mo ti sọ ninu iṣe itan ini pe ọdun keji ti ogun Adubi pari ni Ọba Gbadebọ, Alake ana, waja, ti awọn Ẹgba Ologboni si bẹrẹsi ro ẹniti awọn yio gbe oye Ọba Alake ka fun. Awọn kan ni Ologbe Pa J.K. Coker, ọmọ Ajọbọ ni Iparo Ake ni awọn fẹ ki o jẹ oye Ọba Alake na nitori wahala ti o ṣe nigba ogun Ijẹmọ ati ti Adubi. Pa Coker funrarẹ ni o tọka Ọmọ-Ọba Ladapọ Ademọla fun awọn Ologboni Afọbajẹ wipe on ni oye na tọsi atipe ọmọwe ni on si ro wipe yio mu ilọsiwaju wa si ilu Abẹokuta ija ko ni ṣ mọ, ọtẹ ko si ni si mọ.

Awọn Ologboni afọbajẹ na si gba si i ẹnu, nwọn fi ohun wọn sọ'un lati fi ọmọ Ọba Ladapọ jẹ Ọba Alake na. Nwọn mu lọ si Ipebi ni oṣu keje (July) ọdun 1920. Iyẹn di ọdun mejilelog ji nisisiyi.

Lẹhinti ọba yi ti ṣe oṣu meji ati abọ ninu ile Ipebi na tan ni awọn ba ṣe ẹyẹ igbade-lelori fun un,

Ẹyẹ igbade lori na kamọm, gbogbo ẹsẹ awọn ọmọ Ẹgbẹ ti o wa ni idalẹ ni o pe ṣibaṣiba si ibi aṣeyẹ na. Gomina-agba Sir Hugh Clifford, ti o wa l'Eko nigbana wa ati Biṣọbu Oluwọle pẹlu awọn enia jenkan jankan. Emi paapa ti mo nkọ iwe yi, oju mi ni gbogbo rẹ ṣe.

Bi awọn onilu ti nlulu, ti gbogbo enia si njo ni nwọn nkọrin bayi:

Ademọla joba ilu toro nini.
Ijoye ko binu,
Ẹgba ko mọ binu,
Ademọla joba ilu toro nini.

Gbara ti Ọba yi ti gun ori Oriiye ni o paṣẹ wipe ki nwọn da awọn Oloye Ogboni mẹta ti nwọn ti mọle lori ọrọ Ogun Adubi silẹ. Awọn Oloye na ni Ṣogade, Agbakin Ikija, Lunloye, Balogun Itori ati Laoṣebikan, ẹniti iṣe ibatan Alake alara paapa.

Gẹgẹbi ati mọ wipe onigbagbọ ni Ọba tuntun yi, nigbati o ti gun ori oye tan ni o ba mura lati lọ ṣe isin -idupẹ ninu gbogbo Ṣọṣi ti o jẹ pataki pataki ti o wa ni igboro ilu Abẹokuta.

### Kuti Olorin

Awọn ọmọ Ẹgba jẹ iran kan ti nwọn fẹran orin kikọ pupọ. O tilẹ fẹ jẹ wipe idaji orin inu iwe Ṣọṣi ti awọn onigbagbọ ma nkọ ninu iwe, awọn Ẹgba lo kọ eyiti o pọju nibẹ. Gẹrẹ ti Ọba Alake Keji yi ti gun ori oye tan Ẹl Alufa agba J. J. Ransome Kuti (baba Ologbe "Oawodu" ti Ṣọṣi Ake ti bẹrẹsi con orin ibilẹ Ẹgba ti o ba oju mu ti a o ma kọ fun Ọba tuntun na.

Eyi ni ọkan ninu orin-ibilẹ meji ti Alufa Kuti fun awa Ẹgba fun Oba A'lake ni 1920. Orin na si ba oju mu titi di ọjọ oni. Mo rọ orin na fun anfani awọn onkawe mi awọn ọmọ Ẹgb ti ko mọ gbogbo ọrọ rẹ ri.

(1) Ẹgba Alake ẹ ṣe giri,
Ẹgba Oke Ọna ẹ fi mọ ṣọkan,
K'abẹ Olodumare k'o d'Ọba si,
K'abẹ Olodumare k'Ọba ko pẹ.

(2) Ẹgba Agura ẹ mura ni,
Ẹgba Olowu ẹ giri ẹdọ,
Ẹ jẹ kajọ wolẹ f'Ọlọrun wa,
Kọlọrun d'Ọba Alake si.

(3) Ọba Alake kẹ gbo, kẹ tọ, para Kade pẹ lori ki bata pẹ lẹsẹ,
K Ọlọrun Sẹtẹ ọta fun ayin,
K Olodumare S'apata yin.

(4) Ẹnyin ọmọ Ẹgba ẹ tẹ wọ yia,
Ẹnyin ọmọ Olumọ Abẹluku,
Kabẹ Olodumare ko da wa si.
Kaiye ko tutu kari bigbe.

(Iyoku di ọsẹ ti n.bọ)

# Awon Oyinbo Onisowo Agbaiye Nfi Oja Dabira L'okun (3)

## (Lati Owo Ola Onatade, Olotu "Eleti-Ofe")

### Slovakia

Awọn Oyinbo ilu Czechoslovia ni a ti mọ ni awọn Oyinbo ti nwọn nko ilẹkẹ (beads) orişirişi wọ Nigeria lati ọjọ ti o ti pẹ. Ṣugbọn nigbati Ogun ajakaiye de gbogbo ile iṣẹ wọn ni awọn Jamani (German) gba lọwọ wọn ti nwọn fi nwọn se ile ti ti nrọ nkan ija. Eleyi si mu ki nwọn fa sẹhin diẹ ninu ṣiṣe ẹrọ fun ọja okere.

Lẹhin eyi awọn Alakoso Ijọba ilu na se ara wọn lọkan nwọn dide giri nwọn bọ ṣokoto lati tun ilu wọn ṣe pẹlu nkan idagba soke ilu, gbogbo nkan wa nlọ dẹdẹ nipa iṣẹ owo.

Ni igbati mo de ibi ipatẹ-ọja ilu wọn ni Okun Alasia ni Ọjọ ọsẹ ti o koja yi orişirişi ẹja ni mo ri. O bẹrẹ lori ẹrọ ti nwọn fi ntẹ iwe, ibọn oloju meji

### Norway

ti awọn ọdẹ fi npa ẹran bi agbonrin, ẹtu, igala ati erin ninu igbo, ẹrọ irin iṣẹ, dẹkẹ, oruka, mọto alupupu ati awọn ọja aṣọ mọ bata, orişirişi.

Awọn nkan ti nwọn fi nkọle bi Sinmenti, awo, mọto akero ati kẹkẹ ati kun ọdọ wọn.

Ogunlọgọ awọn enia ni nwọn lọ si ibiti awọn Oyinbo ilu NORWAY fi orişirişi ọja wọn patẹ si nitoripe nwọn fẹ mọ bi ori ẹja panla (stock fish) ti nwọn ti nfi bawa ṣowo ni ilu yi tiri.

Ẹnikẹni ti o ba de ibiti nwọn ko awọn ẹja na si lorişirişi ẹja abọmọfọ a wu Oluwa re jẹ.

### Lebanon

Ilu awọn alawọfunfun ara Lebanon fi ijoko alaramba ti nwọn dara fun awọn Oba tabi awọn ijoye nibi ipatẹ ọja na.

(Wo yoku loju ewe karun)

About Trade Fair:

# Made In Hong Kong...

(By A Special Contributor)

Have you, for instance, ever used a power-driven swizzle stick to take the bubbles out of the after-work drink? The size of a pocket torch, and battery operated these aids to good living are finding a ready market in many parts of the world.

A powerful little motor rotates a nine-inch metal shaft that has two metal discs on the end. The machine can also be used for mixing drinks and beating eggs.

Students of anatomy can take their pick from two products that have just come on to the market.

Made of plastic and designed to appeal to children of all ages are Hong Kong's famous dolls whose curves and dress sense put even the glossiests magazine pictures to shame. As a grim reminder that beauty is only skin deep after all, there is a scale model of the human body complete with removable heart.

In the past, perhaps, the lady was not for burning. Now she frequently is. Hong Kong candlemakers are producing a wide range of Chinese goddess figurines in wax, each guaranteed to give a bright, smokeless light for at least five hours. They come in bright colours that give the appearance of jade and soapstone.

For the mathematically-minded who fined it inconvenient to carry an abacus there is the lightning calculalator, a pocket-size machanical wizard that can add and subtract to six figures.

It is especially useful for totalling bills in decimal coinage.

Also for the traveller is the portable clothes-line, which looks like and is about the same size as a yo-yo. The line unwinds and is re-reeled in exactly the same way as a builder's steel tape measure, and is the perfect answer when a drip-dry shirt has to be hung in a hotel room or other confined space.

Hon Kong is already well known for its competitive prices and if local manufacturers have their way the Colony will soon be equally famous for its ingenuity. The slogan has become: If there's a use for it - well make it.

# It Is A Goal!



**England goalkeeper Ron Springett foils Northern Ireland's inside-left Jimmy McIlroy's attempt to score by dashing out of goal to gather the ball, in the international soccer match between England and Northern Ireland at Wembley, London, recently.**

**The result was a 1-1 draw. Bobby Charlton scored for England after 20 minutes, and McIlory saved the game with a goal a few minutes from the end.**

## Slovakia

Czechoslovak industry suffered great losse during the second World War. The Nazis turned over many factories to war production and mercilessly pundered others. A number were damaged during the fighting or in air raids.

The most pressing post-war tasks were the reconversion of industry to peace-time production, the rebuilding and renovation of factories and the raising of production at least to the pre-war level. These tasks were accomplished by the Two-Year Plan for Economic Reconstruction for the years 1947-48. During 1948 the pre-war level of industrial production was surpassed by 8.5 0/0.

In 1949, the National Assembly approved the first five-year plan for Reconstruction and Further Construction of the Czechoslovak Economy to cover the period 1949-53. This plan set the goal of increasing overall industrial production by 98 0/0 over the 1948 level, with special stress on the development of heavy industry. This plan was fulfilled in both respects. Industrial production rose by 102 0/0.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Norway

Iwọ ti o n a iwe mi, oluko ilu ti mo kọ si oke yi ti nwọn npe ni Norway ni nwọn ti nko ẹja abọmọfọ wa. Bi emi Ayiluka ko tilẹ mọ ilu yi mọ bi awọn enia pataki pataki ni d du ati funfun pade nitori awọn ti o ti lọ si ilu na, awọn bi Ọgbẹni Kujọrẹ, Alhaji M. Ade. Kasumu ti Ayepe ati awọn miran ti nwọn ti ba iṣẹ owo panla lọ si ilu na.

Nwọn ni nwọn mọ enia kẹ nilu na ati pe ori ẹja panla ko jọ ti enia enia rara. Bẹni emi na ti ri ori ẹja panla yi nibiti nwọn gbe fi wọn patẹ si ni eti Okun Alasia l'Eko nio ri abọdọsa ati eyiti ko dẹsan. Ọrẹ ẹgusi ni ẹja panla; awọn Oyinbo ẹlẹja na ni awa ara Nigeria ni a nra pupọju ni gbogbo agbaiye




**Visit Our Stand At The Trade Fair Victoria Island, Lagos.**

## Morocco

Awọn aladugbo wa kan ti nwọn npe ilu wọn ni Morocco ni apa Ariwa ilu Afrika fi ọna awọ dara. Mo gbọ wipe awọ ti nwọn fi nṣe iṣẹ ọna pọ ni ilu awọn ara wa na jaburata. Ti o ba ri ayie de ibiti nwọn gbe fi ọja nwọn si ni Okun Alasia wa ri wipe awọn ara ilu na nnani awọ.

Ni oni ọjọ Ẹti, oni Satide ni nwọn yio se eyẹ ti wọn ni Okun.

## Niger

Lẹhin awọn ara ilu Morocco, awọn ti awọ ko jẹ niya ni awọn aladugbo wa ni Niger Republic—ilu Zabaruma. Awọn ara Eko korin kan wipe Sabaruma nwọn ki lo asọ-aran awọ ni nwọn nro, awọn ilu Niger yi nitotọ ni awọ orișirisi lọwọ lati fi ran aṣọ awọtẹlẹ tabi bantẹ fun lilo ninu oko tabi larin ilu lọwọ.

Ilu awọn arabi na ku jinna si wa pupọ ni Kano, nwọn ko ni koko (cocoa) lọwọ bi tiwa, awọ ẹran ni oko koko wọn.

## Labanon

Awọn Oyinbo ti a npe ni "Kọra" yi ni awọn ni ile ibiṣẹ ti awọn ti ngba agbakọ ile nilu awọn. Awọn si tun ni ile iṣẹ ti awọn ti nṣe onje ipanu bi akara Oyinbo, owu iranṣọ ibọsẹ, ijoko alarambara ti Ọba tabi awọn Ijoye le lo. Bi nwọn ti nfi nkan owo iyebiye se ibi ipatẹ wọn na lọsọ ni nwọn si tun sọ fun mi wipe ọja Aje ọtunla (Monday) ni awọn yio ṣe aṣeyẹ ọjọ ilu ti awọn.




Facts speak for themselves. This venerable veteran, a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,367,000 miles. No doubt it would have gone on if Daimler-Benz AG had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last just as much now as they were then to give many years and many miles of trouble-free, economical service.

VISIT OUR STAND
No 246
AT THE TRADE FAIR.

MERCEDES-BENZ

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (EB) . IBADAN . KANO . KADUNA . JOS . PORT HARCOURT . ABA

SUB—DISTRIBUTORS :

# ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY . ONITSHA . ABA

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 29 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR (OLOTU) OLA ONATADE
15, Kosoko Street, Lagos.

## Oko Iyawo Onibara Pade Agbako Reluwe

Kano—Ogbeni arọ kan Onibara ti orukọ rẹ nje Mallam Ali Dibse ti o sese gbe Onibara ẹgbẹ rẹ ti o nje Doje ni iyawo ni ọjọ Ajẹ (Monday) ti on pẹlu iyawo rẹ na fẹ wọkọ lọ si Kaduna fun igbadun - oniyawo - tuntun, pade agbako ewu ọkọ reluwe bi nwọn ti fẹ wọkọ ni teṣan nibi, apa osi rẹ si ge lulẹ.

Onirohin wa ti o tẹ waya si wa ni gbara ti Onibara yi ti gbe iyawo rẹ arọ na fẹ iyawo tan ni nwọn ti pinnu wipe ki awọn jọ lọ ṣe igbadun a-ṣẹṣẹ-gbe'yawo ti awọn Oloyinbo nfi npe ni honey-moon ni Kaduna nitoripe awọn ti nṣe ngburo bi ilu na ti jẹ ilu Izaji to.

Bi ọkọ iyawo ẹlẹṣẹ kan na ti gbera wipe ki na fo sinu ọkọ ti o sese si ni o ba ṣe "ṣaura" si abe ọkọ reluwe, ọkọ na si ge apa osi rẹ ju silẹ, ni iyawo rẹ tuntun na ba bẹrẹsi sọkun, ti o nkigbe wipe ki nwọn gba on.

## AWỌN ỌLỌTẸ TUN JU BỌMBU SILU ACCRA

ACCRA — Awọn Ọlọtẹ ti nwọn ti nṣe rigbodiyan a nju bọmbu oloro ti npania kakiri ilu Ghana ti tun fọ bọmbu meji silẹ ni alẹ ijẹta ni eti ilu Accra nibiti awọn ọmọ ẹgbẹ oselu ti ida aṣẹ Ijọba wa lọwọ wọn, ti nwọn npe orukọ wọn ni Convention Peoples' Party (CPP) gbe nṣe ere ita, o si ṣe awọn ọmọde meji ni jamba.

Gbara ti rogbodiyan bọmbu oloro yi ti ṣẹlẹ, ni awọn ti o wa nibẹ ti fi moto ko awọn ti o ṣe leṣe lọ sile ti nwọn ntọju awọn alaisan, awọn Minisita oniṣe Ijọba meji, awọn Ogbẹni Kofie Baako ati Kwaku Boateng pẹlu awọn Ọlopa'nu ati awọn ọga wọn ti de ibẹ.

Ọrọ na ru awọn alakoso Ijọba loju nwọn ko si fẹ jẹki awa oniwe irohin mọ okodoro rẹ, Iye gbogbo awọn ti bọmbu oloro na pa nwọn ko ti sọ fun araiye gbọ titi di bi a ti ntẹ irohin yi jade.